# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,577 SATURDAY DECEMBER 4, 1965 (2D)


## Abiyamo Kan Ku L'Ojo Ikunlẹ !

IBINNI:– Jinnijinni dabo gbogbo enia ti nwọn wa ni Ile Itọju awọn Abiyamọ ati Aboyun, nigbati Obinrin kan, Iyaafin Anyansi na si ku bamubamu lẹhinti o bi ọmọ na tan ni ana ọjọ Ẹti ti ise ọjọ kẹta oṣu yi.

Olutọju awọn Abiyamọ ti o wa ninu ile itọju awon Aboyun na ṣẹ alaye fun oniwe irohin wa ni Ibinni wipe ni dede agogo mẹta oru ni Obinrin na bi'mọ, nigbati o si bi'mọ na tan, nṣe ni ẹjẹ bẹresi jade ni ara rẹ

Nigbati on si se akiyesi wipe ẹjẹ ti o njade lara Obinrin na ti pọ pupọ ju, ni on ba sare lọ ṣọ fun Dọkita ti o wa ni ẹnu isẹ nigbana, ṣugbọn Dọkita na ko wa ṣe itọju Obinrin na titi Obinrin na fi ku !

O tun sọ pelu wipe ni dede agogo merin oru ni on lọ pe Dọkita na. ṣugbọn nigbati o di agogo meje owurọ ọjọ keji nigbati Dọkita na fe malọ si ile lo to wa da on lohun wipe. 'Obinrin tio npe mi fun na da, ṣe o ti bi'mọ tan'

Nigbati Irohin yi de ọdọ awọn enia Obinrin na, nse ni gbogbo wọn ka'wọ le ori ti nwọn si nsunkun ti ariwo ẹkun si gbojikan yika gbogbo ile Iwosan na titi ti ilẹ ọjọ na fi su.

Irohin fi ye wa wipe awọn enia Obinrin na sọ wipe awọn yio pe Dọkita na ni ẹjọ nitori pe on lo se iku pa iyawo awọn ti o wa bi'mọ


WO OJU EWE KEFA


## Nwọn Tun Da'na Sun Mọto Ijọba Ni Ikare

# MINISTA BẸLUGBẸ, ADAJỌ WA NI ILE IWOSAN!

IKARẸ:— Ariwo ta gee, okiki kan kuu, gbogbo awọn enia si bẹrẹsi sare ọlọmọngbọmọpọn nigbati awọn enia kan gburo wipe ọkan ninu awọn minista Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bọ wa si inu ilu won ti nwọn si lọ d'ena de Minista na ni o ju ọna wipe ki o ma ba ṣe le kọja wọ inu ilu wọn lọ ni ijẹta ọjọ ọjọ 'Bọ ti isẹ ọjọ keji oṣu yi.

## AṢE'YI ṢE AMỌBUN O!



Aworan oke iiye yi ni ti Oloye Iyaafin Awolọwọ eniti o ṣe iranti ajọyọ ajọdun adọta ọdun ti Oloye na de aiye, eyiti nwọn ṣe ni ilu rẹ Ikẹnne ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrindinlo gbọn oṣu ti o kọja lọ yi.

Aworan ti ẹ nwo ninu iwe yi jẹ ọkan ninu awọn aworan ti Oniwe Irohin wa ya ni ọjọ na nigbati Oloye Iyaafin Awolọwọ fẹ ge akara ọjọ ibi rẹ ni ọjọ na.

Aworan ti awọn oniwe Irohin wa ya ni ọjọ na le ni mẹdogun, ẹ o si tun maa ri awọn aworan yoku ni orisirisi lati igbayi lọ ninu iwe Irohin wa laipẹyi.

Bakanna ni ẹo tun ma a ri awọn aworan ti awọn Oniwe Irohin wa ya nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ Af nifẹre Eko fi nṣe eyẹ fun Iyaafin Oloye Awolọwọ ni Eko ni ibẹrẹ ọsẹ yi.

Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ki Oloye Iyaafin Awolọwọ ku orire, a si tun gbadura pẹlu wipe ki Ọlọrun jẹki ẹmi rẹ le ṣe ọpọlọpọ ọdun laiye, ki o ma si ṣe ṣe eleyi ni aṣemọ o. Ẹ ku ọdun.

Gẹgẹbi Irohin ti a ri gba lati odo Oniwe Irohin wa ni Ikarẹ ni alẹ ana, a gbọ wipe gbogbo awọn Obinrin Ọloja inu ilu Ikarẹ ni nwọn tapanpa ti nwọn si binu da Ọja wọn silẹ wipe awọn ko faramọ ọna ti Ijọba gba dibo ti o kọja lọ yi.

Igbati awọn enia na ko mọ ohunti nwọn yio ṣe ni nwọn ba pe ara wọn jọ ti nwọn si ṣe ipade. Ninu ipade ti nwọn ṣe ni ibẹrẹ ọsẹ ti o koja lo yi ni gbogbo awon Obinrin Ọloja inu ilu na gbe pinnu wipe, awon ko ni ta oja awon titi ti Ijoba yio fi da awon lohun ẹbẹ awon.

Ninu ipade yi ni awon enia na ba ti ṣe da imoran wipe awon yio to yika gbogbo arin ilu lati fi ipinnu awon han awon Ọba, Ijoye ati gbogbo awon ara ilu wipe, awọn ko faramo ọna ti nwon gba dibo ti o koja lo na yi.

Şugbọn nigbati awọn enia na nto kaakiri ni nwọn ba gburo wipe ọkan ninu awọn Minista Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni D. K. Olumofin nkọja lọ ni oju ọna nib ti nwọn gbe nto kaakiri were ni awọn enia na ba duro ti nwọn si nreti Minista na wipe ki o de wa ba awọn bi o ba laiya rẹ la ti le de arin awọn tabi lati gba arin awọn kọja.

Ko pẹ pupọ lẹhin eleyi ni nwọn ri Minista na ti o nbo ninu moto Ijọba kan nomba WNG 5, on pelu adajọ kotu ijọba ibilẹ kan Ọgbẹni O. Daniel ti nwọn jijọ nbọ. Bi awọn eniana ti ri mọtọ na ti nwọn si wo inu rẹ ti wọn ri Ọgbẹni D K Olumofin were ni nwọn ba da mọto na duro ti nwọn si ṣuru bo Minista na.

Nigbati Ọgbẹni Olumofin ri wipe ọrọ na nle ju bi o ti ṣe yẹ lọ ti o si tun ṣe akiyesi awọn enia na wipe nwọn ti mura tan lati lu on pa we rẹ ni o ba sare jade ninu mọto rẹ ti o si salọ mọ awọn enia na lọwọ.

Bi awọn enia na ti ṣe wa Minista na to ni ọjọ na won ko gburo rẹ ti ti di igbati a fi nkọwe yi lọwọ.

Nigbati Dirẹba rẹ ri bi nwọn ti ṣe nle ọga on' ni o ba fẹ maa sare g e moto rẹ salo, ṣugbon awon enia na ko fun un laye lati kọja, ni nwon ba da ṣẹria fun Dirẹba moto rẹ na ti nwon si lu u ni ilukulu.

Lẹhin na ni awon enia na tun wa ṣe akiyesi wipe ẹnikan tun wa ninu moto ayokẹlẹ na, nigbati nwon si boju wo inu moto na ni nwon si ri Ọgbẹni kan, ẹni ti iṣe okan ninu awon adajo Kotu Ijoba Ibilẹ' nwon si lu on na ti o fi jẹ wipe ko le dide.

A gbọ wipe nwon ti gbe Dirẹba na ati Adajo lo si Ile Iwosan nibiti nwon ti njẹ irora lowo nisisiyi. Lẹhinna ni awon enia na wa ṣa ina si moto ayokẹlẹ ti moto na si jona rau rau.

Onirohin wa fi ye wa pe, awọn enia na si tun nwa Ọgbẹni Olumofin lọwọ bayi, ṣugbọn nwọn ko ti ri i, nwọn ko si mọ ibiti o gbe wa pelu titi di igbati a fi nkọwe yi lọwọ.

Ọkan ninu awon Obinrin Ọlọja na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa wipe, o ya awọn lenu lọpọlọpọ bi Ọgbẹni Olumofin ti ṣe le ri aye salọ mọ awọn lọwọ bi awọn enia na ti ṣe pọ to.

Irohin awọn Ọlọja Ilesha sọ fun wa wipe awọn ko ti ri ẹnikankan mu ninu awọn enia ti nwọn sa ina si moto Minista na ti nwọn si tun ṣe adajọ Kotu Ibile ati Dirẹba Minista; bi nwọn ba ri awọn enia na mu, ẹo ma a gbọ o.


**FIXED ODDS NAPS**

Sure 3 Draws For this Week

Exeter v's Gil'Ham xxx B

Nott. For v's Leicester xx B

Ipswich v's Rotham xxx B

Bank on it.

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Ọro Naijiria Nfẹ Amojuto

Bi a ba wo gbogbo ohunti o nṣẹlẹ ninu ilẹ Naijiria ao ri wipe gbo gbo nkan ti baje lati bi ọdun mẹsan, nkan ko lo deede mọ, o wadi rudurudu gbogbo rẹ ko ni ojutu mọ titi fi di akoko ti a wa yi.

Lati igbati Apapọ Ijọba ti ṣe ofin pajawiri ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni nkan ti bajẹ ki o to tun nbajẹ siwaju si titi di oni yi kaka ki ewe agbọn rọ o tun nlesi ni.

Mo bẹ gbogbo awọn ọmọ Naijiria ki nwọn jẹ ki a ronu wa d da ki a wa ọna ti orilẹ ede wa yio fi dara ni asiko ti wa.

Ki a ma da ọrọ na da awọn oṣelu wa nikan gbogbo wa ni ọmọ Naijiria, a si ni ẹtọ lati tun ile wa ṣe fun arawa ki a yago fun iwa Keeta lagbaja Ibo Tamẹdu Hausa ati Lamorin Yoruba. ki a ṣe ara wa ni ọmọ iya.

Ẹ ku iṣẹ Olotu

Emi ni
B O. Ọlalere.
IBADAN.

## Ẹ Ku Orire

Olotu gba mi ni aye diẹ ninu iwe jẹ oloyin mọmọ ti o kun fun ọgbọn ati oye lati ki Balẹ Orimadegun Ijọmu Oro lori oye ti awọn enia Ilọrin jẹ lati ọdun marun sẹhin nigbati awọn enia kanbi bẹkọ ti o si wu Ọlọrun ti o fi Oloye Orimadegun jẹ oye idile baba rẹ.

Adupẹ ti Ọlọrun si pari ija larin awọn enia ti ndu oye na ni ọjọ kẹfa oṣu kefe ninu ọdun yi Ogunna gbongbo ti ndatọ lẹnu igbin Ọba Sulu Gambari ti so pe Orimadegun ọkọ Morẹnikẹ ni o ye na ṣọ si o si tun pe wọn ni ọjọ keji oṣu ejọ ninu ọdun ti a wa yi

O si sọ fun wọn pe on ko gbọ dọ tun gbọ ija ni arin wọn mọ lati ọjọ na

Mo bẹ gbogbo awọn ara ilu Ijọmu Oro pe gbogbo ohunti Balẹ Orimadegun ba sọ fun nwọn niki ẹ ma ṣe o Ọlọrun yio ma ran wa lọwọ o (Amin)

Mo si tun ki awọn bi Ọba wa Ọloro ti Ilu Oro ati awọn ti o tun tẹle Balẹ Orimadegun lọ si ilu Ilọrin

Balẹ Orimadegun ẹ ku abo ye o Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi Ikẹ Igẹ Ọlọrun yio ma ba nyin

Emi ni
J. Anikẹ
Ijọmu – Oro

## Awon Omo Ijẹbu Fa'mo Yo

Olotu:- Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin ti kun fun ọgbọn ati oye lati ba awọn ọmọ Ijẹbu ti mo ri ki ninu awọn Iwe irohin pe nwon ti binu fi ẹgbẹ olowo dudu si lẹ fun Oloye S musi Ladoke Akintola ati olori ẹgbẹ na ni Iha Gusu Ijẹbu ọgbẹni Alfred Folorunsho odulana

Eleyi fi han pe omo eko ni awa omo Ijebu ati pe o si jẹ ohunti e ti emi nikan loju pupo lati ma gbo wipe awon Ijẹbu kan wa ti nwon je olowo ti a npe ni Dẹmọkrat ti ko tọ ki a ma gbo ni ekun Ijẹbu

O ye ki a fi ti Baba wa Alaiyeluwa ọba Samuel Akinsanya Ọdẹmọ ti Ishara kọgbọn nipa Akitiyan rẹ ati nwon ṣe owo rẹ ku si kọbọ kan ṣoṣo lodun ko ti tori na ṣe ẹgbẹ Dẹmọkratu nitori eyi ẹ jẹki a fi ti Baba wa na ṣe iwa hu ki a kọ oju kikoro owo osi sile ki a duro lẹhin omo wa, Baba wa Oloye Awolowo



OLOYE AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Emi ni
Bayo Tiamiyu
Eko

## Ilu Edidi Nkọ

Olotu inu mi ilo dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu Iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye ti o tun nta bi akara gbigbona lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ile Naijiria lati ba wa mu oju to ilu wa Edidi ati pe ki nwọn tun ṣe eto bi awọn ohun ilọsiwaju si ilu wa

Ninu awọn ohunti a nbere ki Ijọba Ipinlẹ Ariwa ṣe fun wa ni oju ọna ọlọda ina manamana, Erọ omi ati awọn ohun ilọsiwaju mi ran ti yio mu ki ilu wa ni ilọsiwaju ju ẹgẹbi o ti ṣe wa tẹlẹ.

Gbogbo oju ọna ilu wa ni o ṣe ri fun awọn onimọto ati awọn onikẹkẹ pẹlu bẹẹni awa enia ilu na ki ifi owo ori wa jafara ṣugbọn ko si iranlọwọ kankan ti Ijọba Ipinlẹ na se fun awa enia ilu na.

Inu wa yio dun bi awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba le ṣe Iranlọwọ fun awa enia ilu na.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi

Emi ni
Agbo Ọla Awo
EDIDI


# ẸGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI

**"CYCLEVEN"**

Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya lo le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu kuro ni. pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun nię iyonu rẹ yio si too ma bẹrẹ baka na, Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke yiogere (Basikulu) pupo elomiran ewa nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jẹdijẹdi orişirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi to ba nyo ti o ba ṣe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu omusu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi rẹ ko ki o si danwo o işi meta ni o dalu wipe iwo yio bo lowo Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Naijiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store
8, Palm Church Streer Lagos,
Phone 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
LAGOS



# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awọnOnibara wa pe. Iwe Itumo Ala. Iṣẹ Wiwo, ọjọ ibi Ọmode lati Ọgun Ajebidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan.

A si tun ṣẹṣẹ ṣe Iwe Itumo Ala miran ati iwe Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni, ẹyọ kan, mejila tabi dosin rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street
Mushin.

A si nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin

# Ija Awọn Ọdẹ Ile--Ifẹ Nigboro Ilu Alọ (Apa 6)

LATI ỌWỌ ẸSỌ

Lẹhin ti awọn ọdẹ ile Ifẹ ti pari ijakadi wọn pẹlu awọn Ọbọ, Inaki, Akiti, Lambẹ, Ijimere ati Lagido ati awọn şaşa ẹ ẹrẹ wọn Aeya r wọn joko nwọn sinmi nọ on si nfi ẹrọ omitoro ọrọ beni nwọn kan dede ni awọn Egbere ti nwọn şeyo gẹgẹbi ewọn Ẹyọ Olokun kia lesẹ katu ni ọdẹ kan ti nwọn nre ni Werepe Baba Igi dide o wi fun awọn Ọdẹ ẹlẹgbẹ rẹ wipe Ẹ yin omo iya mi ẹ ẹki a pa Iji han Iji ki ẹru ba le ta Iji Tani awon Egbere gbere u nwon to wa tani nwon tilẹ nfi enia ava ha nse ẹgbẹ wọn ti nwon fi jade to wa lati ba iwa ja awọn ẹru Oni gbo nwon yi.

Inu bi awon Egbere na nigbati Werepe Baba Igi pe wọn ni ẹru O nigbo nwọn si pakura siwaju bẹni Werepe ni ado kan ẹfufu lẹle kan si ti ẹdọ awọn Ọdẹ ile Ifẹ fẹlọ si odo awon Egbere o wa ni kini kan silẹ ti o dabi iyerosun a şe Werepe lo tu silẹ. Ko ju iwọn işẹju mẹwa lo ti awon Egbere na bẹrẹ si fi owo jara ti uwon si nke Iboni Iya o! Baba o! ebi ni o di ohun ti awon Eggere awi titi d'oni wara-were awon Egbere laka

Gẹrẹ ti awon Egbere salo tan ni ako Erin ti o da gbogbo rogbo diyan yi silẹ wa nfi orija igbobo-wa odẹ kan to nje Ajantele dide lo lati ba Erin na woya ija o tẹ ofo bo ẹmi o si pe Ajantala ki o ba on ko Erin na ni owo. Ajan tala lalẹ yo ni ẹgbẹ erin na, o si ko pantore bo Ajanaku na, o naa tobe ti o fi daku Ajantala rope o ti ko lo ba fi silẹ Ọdẹ ka ti nwon npe hi Arikijobi o yo obe o fe bere si kun Erin na lojiji ni Erin şeji ti o si salo ni awon Ọde ba bere si orin wipe, Erin goke o şe, Agan Erin goke Alo

Itan na koni pario digba mi—rao.

## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUKIUS ( an 22 Fe 20) Idamu yio wa fun ọ larin awọn ẹbi rẹ ati Idamu ọkan yio wa fun ọ ti yie jẹki sẹwẹsi ba ọkan rẹ loni, şugbọn aşalẹ ọjọ oni, yio ni ahadun jojo.

PISCE (Feb 21 Mar 20) Ọjọ oni dara bi o ba rin irin faaji lọwọ obiri lọ kan şe e faaji lọ,

ARIES (Mar 21 Adril 20) Gbogbo ohunti o jẹ isoro fun o ni yio di irorun apejọ awon egbe ti mbo yio gbeo ga soke fi oju si daradara maşe jeki owo re ju

TAURIUS (April 21 May 31) Mase kanramo ẹnikan nsa ri ki o fa gbo awon to nife mora ohun kan ti ti so nu ti a si tun ri yio (eki ija pari

GEMINI May 21-June 21 Nigbati o ba wa lẹnu işẹ ati nigba to ba wa lẹnu faji ẹkanairotẹlẹ kan ni lati şẹlẹ maşe fi ẹnu işẹ rẹ şere nitoripe dide ni ọla rẹ mbọ wa

CANCER June 22-July 22 Oluwa yio fun ọ ni agba ra atunşe ni akoko yi na lo yẹ lati şe atunşe gbogbo ija to ti mbẹ nilẹ Aşalẹ o i yio gbadun fun ọ pipọ

LEO (July 23 Aug 22) Ẹnikan yio wa lati ri oju re re maşe kọ lat se iranlọwọ fun ọluwarẹ io ọ yio si ri aye lati se ọpọlọpọ ohun isoro

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Oni ni ojo ti o dara lati lo kesi awon orẹ rẹ a i lati lo ra oja titun wa sile

LIBRA (Sept 23 Oct 23 Sa gbogbo agbara rẹ lati mu k gbogo won to sunmo o nifẹ rẹ daada pelu awon to da a a ile rẹ tabi aladugbo rẹ

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Ọr kan nipa iwe yio şẹlẹ ẹnikan alejo ti o mbọ wa bi ọ ni yio jẹ i igbadun ale ọlọ oni ko ni gbadun.

SAGITARIUS (Nov 23 Dec 21) Iwọ yo şe orire ni na fifi o i ka ti si ti awa yi tẹ ọ lọwọ, ko si jbru

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Gbogo oro ti o ba tẹ o lowo loni ki o ma dani şinşin ko di hi nwon ba gwe pe o maşe aladehun oni si dara fun o bi o ba nta tete.


## IWE KOŞEMANI NI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo 'YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da şe AYẸWO fun ara rẹ

"KOŞEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Post ge 9d tete lọ ra tirẹ ko to tan

FI OWO RANŞẸ SI -

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA.
Leti Ọja Jankara L'Eko



# Kere o Kere-o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi şe ọrọ ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan jọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo girikl ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ojọ rẹ pẹ to hẹ na ni nwọn si tun fi ọ ọ sọya tabi po ile i fun gbo bo awọn ti amedi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun n'gbakugba ara wiwo, Ẹsanr ẹhin didun s san ati aiko riran kedere ko d ro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ẹia ti nwọn ẹnba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹj şe enia nipa sis d ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mẹfa abọ (6/-6 pe e Igo kekere şile mẹta abo 3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Şọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787

# KANJUKANJU IṢORO IDASILẸ IṢIPOPADA

### Latl Oju Ewe Keji

wọn fun gbogbo enia ki o maṣe si enia kan ti ko ni ri iṣẹ ṣe ninu ilu na,

Ninu ẹdẹgbẹta awọn ilu iṣẹ ti Ijọba Orilẹ ede awọn Rọsia ti pese fun awọn enia na lati da silẹ ninu ilu wọn yi awọn Alaṣẹ Ijọba na ti pari adọjọ (150) ni nu rẹ. ti nwọn si ti bẹrẹsi ṣiṣẹ nibẹ pẹlu nisisiyi.

Nitori ọna ti awọn Ijọba Rosia ngba ṣe iranlọwọ fun awọn Orilẹ ede kekeke wọnyi ti awọn Ijọba Alagba ra aiye miran ri, ni awọn na fi nṣe alekun iṣẹ ati owo fun wọn lalko tun fi ipa mu wọn ṣe ohunti awọn enia na ko ko fẹ lati ṣe mọ

Ohunti awọn enia na nṣe yi lo mu ki awọn Orilẹ-ede ti awọn nṣe iranlọwọ owo fun ki o le ma a ṣe gbogbo iṣẹ ti nwọn fẹ ṣe, laiko si ijaiya ati ibẹru nibi gbogbo fun wọn, nwọn si nle se e ohunti nwọn ni lọkan lati ṣe gẹgẹ-bi ero ọkan wọn

Ninu ọdun 1960 ni. Ajọ Igbimọ agbaiye ṣe ofin, ti nwọn si da ni imọran fun gbogbo awọn Ijọba alagba ra orilẹ ede aiye pe ki wọn fungbogbo awọn orilẹ ede to ba wa ni abẹ wọn ni ominira

Ninu odun 1956 titi di ọdun 1958, ipinnu tl Ijọba orilẹ ede Rosia ṣe yi lo jẹki Ijọba Arab a ni apapọ ida-silẹ ni ara ilu Egpti ,Syria ati Iraq.

Bakanna ẹwẹ ninu ọdun 1961 titi di ọdun 1962 Ijọ-ba Rosia lo ṣe olugbọwọ fun Ijọba orilẹ ede Kuba ki nwọn to le gba ominira kuro labẹ Ijọba Amẹrika oni yi Ijọba Rosia si tun nse onigbọwọ fun ijọba ori lẹ ede Vietnam ki awọn na le bọ kuro ni oko ẹru ki nwọn si gba ominira

Ki se eleyi nikan, Ijọba Rosia tun nṣe iranlọwọ nisi yi fun awọn Ijọba orilẹ ede Yemen Algeria Indonisinia ati Ijọba orilẹ ede miran pẹlu ki gbogbo wọn le wa ni ominira.

Ọpọlọpọ awọn iṣẹ ni Ijọ-ba orilẹ ede Rosia nṣe fun awọn orilẹ ede kekeke ki nwọn le gba ominira ninu ogun ajakaiye keji, orilẹ ede diẹ lo wa ni ominira nigba na, sugbọn larin ọdun m... ...ta ni atia ọdun 19-46 titi de 1950 orilẹ ede mẹ tala (13) lo gba ominira.

# YẸYẸNATU

### Lati Oju Ewe Keji

naa ni iyen sa o

Yeyenatu Ootu ni sugbon Akintola feran Yoruba tobe ge ti o fi korira aṣa Yoruba Ṣebi nitori pe ko le gba aṣẹ lọwọ Awolọwo ni ija se de?

Olotu:- gbagbe yẹn awọn agbagba ti dide lati pa ri rẹ nisisiyi,

Yẹyẹnatu:- Lootọ? nibo ni awọn agbagba na wa? Nwọn ṣẹṣẹ de lati Mẹkka ati Mẹdina ni? Tabi ni bo ni nwọn lọ lati ọjọ yi.

Olotu:- Mwọn ngbiyan ju lati pari rẹ na ni

Yẹyẹnatu:- Se ki iṣe ni nu wọn ni o nyọ tuo Akintọla pe ẹgbẹ rẹ tun wọle?

Olotu: Emi ko tilẹ mọ?

Yẹyẹnatu: Ipẹ wo ni a fẹ ṣe fun ẹni ti ẹkun pa iya rẹ? Adegbenro gbe apo ti awọn ẹgba dibo nwọn ko jẹ ki nwọn ka ibo bẹẹni awọn ti ofẹ pari ija le paṣẹ ki awọn ka ibo yi kiakia ta bi? Ẹ ma tanwa jẹmọ olotu

Olotu:- Rara nwọn fẹ pari ija looto ni

Aanu Adegbenro ni o tilẹ nṣe nitoripe bi o tilẹ bọ si ijọba ni west ko sowomọ

Olotu; Owo wa Oloye Akintọla ti sọ pe owo wa

Yẹyẹnatu; Ṣe eyiti o sọ ti awọn alufa? Iyẹn nipe o korira awọn agbẹ ni tabi

Olotu: Rara o ko si ẹniti ọkunrin yẹn koni ifẹsi

Yẹyẹnatu: Lootọ ni ko ri ko sun ni on ati Okpara paapa.

Olotu O le kọwe si ko bere

Yẹyẹnatu Ija ni?

Olo tu Ija kọ ẹyin ọmọ Yoruba ti gbọn ju loju ara nyin

Yẹyẹnatu Lootọ ni iyẹn ni Akintọla ṣe nba Hausa ṣọrẹ ti o si nsọ fun wa pe ika ni awon ti ibo ti nba Yoruba ṣe ọrẹ.

Olotu Nigbawo lo sọ bẹ?

Yẹyẹnatu NNDP ni awon ibo ni o fa rogbodiyan si West ni.

Olotu Irọ ni yẹn tabi otitọ?

Yẹyẹnatu Lọwọ mi ni ẹ ti ubere? o dara Hausa ani oṣelu ati ọlọpa Hausa lo fa ijọgbọn ati pipa alaimọkan ni West, Irọ ni iyẹn tabi otitọ ?

Olotu: Emi ko mọ.

Yẹyẹnatu Hahẹn emi na ko mọ Mo si ro pe o yẹ ki a ro o,

Olotu Riro kan ko si nibẹ bi ki Ọlọrun ba wa tun West ṣe o.

Yẹyẹnatu Ṣe enia Ọlọrun ni wọn pe Alhaji Balewa ki a ma a wo ohunti yio ṣe ati pe bi ko ba ṣe nkankan igba yẹn ni emi yio wa gba lọkan mi pe lootọ awọn Hausa lo fẹ pa West rẹ

Olotu Iyẹn tirẹ nko ba ọ sọrọ gbogbo aiye ẹ gbọ nko ba sọrọ

Yẹyẹnatu Ha ojo ọkunrin o dabọ


## Ha! Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ-

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ẹyan ati idun.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBENLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,577 SATURDAY DECEMBER 4, 1965 (2D)


## Ẹgbẹ Arowosafẹ Fẹ Ṣe Ajọdun

EKO. – Ninu irohin kan to de ọwọ wa lati ọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ Arowosafẹ ti iṣe ẹgbẹ ọmọ Ibilẹ Koko ti ẹka Eko ni awọn ti ṣe alaye pe awọn yi ṣe ere aladun kan ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni nọmba 87 Lewis Street, Eko.

Irohin na tun fi ye wa pe ẹniti yio ṣe ere alarinrin na fun awọn ọmọ ẹgbẹ ni Alagba Iranmidimeji Olọmọ-wewe eyiti Alhaji Alapo iṣe olori wọn.

Ayẹyẹ ere ọjọ na yio bẹrẹ ni deede agogo mejọ alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ati pe awọn elere ọjọ na yio si ṣe ere titi di owurọ ọjọ keji ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

Gbogbo awọn ọmọ ilu Koko ni jakejado ilu Eko ati agbegbe rẹ ni irohin lati ọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ fi ye wa pe yio pese sibi ayẹyẹ ere ọjọ na ati pe ere ti awọn ẹgbẹ na yio ṣe ni ọjọ na yio si jẹ ọkan ninu awọn ere ti awọn ọmọ Ibilẹ ilu Koko ti ma nṣe ni ilu Eko ati agbegbe rẹ ati pe gbogbo awọn enia jankanjankan ni yio pese sibi ayẹyẹ ere ọjọ na.

# ỌGBẸNI AKINYELE PADA ṢI ẸGBẸ AFENIFERE

ONDO Ni ibẹrẹ ọsẹ to koja yi ni Ọgbẹni G I Akinyẹle kede sita pe on yọwọ yọsẹ ninu ẹgbẹ Dẹmọ nitoripe nwọn kowa iro ati alafia awọn mẹkunnu apo nwọn lasan ni nwọn nja fun ati wipe aiye ko fẹran wọn Ọlọrun na tun kọ ẹhin si wọn pẹlu.

Gbara ti Ọgbẹni G I Akinyẹle ọkan ninu awọn agbẹjọro pataki to wa ni ilu Eko ti sọ fun gbogbo aiye gbọ pe on ko ṣe ẹgbẹ Dẹmọ mọ laiye ati lọrun ni oniwe rohin wa ti o wa ni Ibadan ti lọ fi ọrọ wa Ọgbẹni Bọla Ige Akọwe eto irohin ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ile Naijiria lẹnu wo nipa ti Ọgbẹni G I Akinyẹle ti o fi ẹgbẹ Dẹmọ sile bọ si ẹgbẹ ọlọpẹ.

Esi ti o fun oniwe irohin wa ni pe ki iṣe ọrọ ti o kan apapọ ẹgbẹ Afẹnifẹre o ni ọrọ na wa ni ikawọ awọn ọmọ ẹgbẹ ti o wa ni agbegbe ilu rẹ ohun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ba wi ni abẹ gẹ bi awọn ẹgbẹ na ba ti gba inu awọn dun si pẹlu.

Lẹhinna ni oniwe irohin wa tun lọ ba Oloye G B A Akinyede ẹniti o jẹ olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbegbe Ondo nipa ti Ọgbẹni Akinyele ati ero awọn lori rẹ esi ti o fun oniwe irohin wa ni pe njẹ nkan ẹni le di meji ki inu o tun maa bi ni? awọn gba tọwọ tẹsẹ awọn si dari ji patapata nitoripe aṣiṣe kan ogbon.

Oloye Akinyede sọ wipe kikuro ti Ọgbẹni Akinyẹle kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ fi apẹrẹ rere nkan ti yio dara han o ni ẹgbẹ Dẹmọ ki iṣe ẹgbẹ oṣelu rara bikoṣe awọn ti nwa anfani ki awọn awọn aṣẹ loju on le yọ lu gbogbo awọn to fẹ jẹ pe nwọn ti da ẹgbẹ nwọn ati o jẹde kan Judas ni awọn jẹ.

O tun sọ siwaju si pe iṣe ti awọn ti awọn wa ni okun Ondo nṣe ni wipe, awọn nwa idera ifọkanbalẹ paapa awọn ti o mu agbe to rẹ jẹ awọn ti nwa iṣẹ ati awọn ti o ni ifẹ ilu awọn. Ikan ti nwọn ko jẹ ti ọkan wọn nitori awọn Oloye Akinyede sọ pe ẹgbẹ ọlọpa ti di ti gbogbo aiye o si wa fun awọn, ẹnu ti o ṣe tan lati ẹnu awọn fun akan rere orile ede yi.

Oloye Akinyede tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ki Ọgbẹni Akinyele ku abọ sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre a si mo wipe "o ṣe ku ti ibọn dan, nitorina ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ yio tun pada wa wọ ẹgbẹ Afẹnifẹre o ni aye si run wa fun wọn pẹlu.

### ỌRỌ DẸMỌ KOLESI

Ọgbẹni G. I. Akinyẹle, ẹniti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ninu ile Igbimọ Asofin ti Ipinlẹ Iwọ Orun ti o si wọle ni arin ekun Ondo ni o sọ fun oniwe irohin wa pe ko si ọrọ otitọ kan ninu ọrọ ti ki iwe otitọ rara irọ fun balai ni gbogbo rẹ,

Ninu ọrọ re ni o tun sọ pe, gẹgẹ bi ẹgbẹ Dẹmọ ti awọn ṣe ileri idibo si ile Igbimọ Aṣofin ti ipinlẹ Iwọ Orun, o ni gẹgẹ bi ọmọ ilu Ondo ti on tun jẹ akapo fun ẹgbẹ Dẹmọ, on mọ nkan ti o wa ni Ondo ju ẹniti ki iṣe ọmọ ilu Ondo ti o fi ara rẹ jẹ Akọwe ipolowo fun ẹgbẹ Dẹmọ,

O tun tun nsọ fun Oloye Akinyede ki o ti ṣe ... ki awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ le pada wọ inu ẹgbẹ Afẹnifẹre, o wa pari ọrọ rẹ pe ... Ọgbẹni Akinyẹle alewo loju gbogbo ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre.

# Iyawo Ile Kan Wẹwọn Oṣu Mejila

YABA:- Oju gba gbogbo enia ti o wa ninu ile ẹjọ kekere ti Yaba ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kini oṣu yi labati Ada, jọ ile ẹjọ na paṣẹ pe Obinrin abiyamọ kan ti oruko rẹ nje Morisọla Gbadamọsi ni ọdun mẹdọgbọn lọ si ẹwọn oṣu mejila igbati Adajọ ile ẹjọ na ri Ọdaran Obinrin na jẹbi ẹsun ti Ọlọpa ka si lẹsẹ,

Gbara ti obinrin na gba idajọ ni o ba bu puru ẹkun ti o ni Enyin enia ẹ mojuto awọn ọmọ on ti o wa nile ki ato de lati ọgba ẹwọn.

Ẹsun ti awọn ọlọpa ka si odaran obinrin na lẹsẹ ni pe, o wọ ile orilẹ lati gba aṣẹ o si tun ko nwọn lẹru pẹlu Ni ọjọ kejidin

lọgbọn osu kẹjọ ọdun yi ni arabinrin na lọ ile Ọgbẹni Bandele Sule ni Nọmba 89, Griffith Street Ebute Meta ti o si ji Golu ọrun eyiti iye owo rẹ jẹ poun mejidin sile meji ohun ini ọmọwumi Sule gbe

Ọdaran Obinrin yi gba pe on jẹbi awon esun mejeji ni ni

adajọ ọgbẹni O. Agbẹdu ba ni ko lọ si ẹwọn ọdun kọọkan fun ẹsun kọọkan ki o si lọ pọ ni ẹkanna.

K Adajọ na to ṣe idajọ le ọdaran na lori ni o ti bi lere re, "kini o fẹ sọ si ẹrọ yi?" O jẹbi ni tabi o jẹbi? Obinrin na sọ pe oi on ba ni on ko jẹbi o ni ko si ẹniti yio duro fun on.

Adajọ ni on mọ bẹ nito otọ nitoripe nibẹni aṣọ ibora rẹ wa nitorina mo ni lati ṣe iṣẹ mi monsọla gba pe nitootọ on ko jina si ẹwọn.

---

## Abiyamo Kan Ku Lo-lo Ikudlẹ

### Lati Oju Ewe Kini

A gbo wipe Minista Ala mojuto eto ilera fun Ijoba Ipinle Agbedemeji Iwo oru ti kowe si Dokita n, ati Oludari ile Iwosan n wipe ki nwọn tete yara so ti won lori isele buruku to sele ni nu ile Iwosan na kia kia

Bi a ba ti tun gbo ero na si, ẹ o tun maa gbo o


Printed & Published by Modupe Printing Press 10, ... Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 4/12/65